**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (8)**

**Ìjẹ́wọ́: Orìn Dáfídì 107:20: Ó rán Ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Ó sì mú wọn lára dá, Ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn.**

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Ayànmọ́ mi, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, kọ ìbọ̀dè-kí-ìbọ̀dè, ní orúkọ Jésù.
2. Mo kó gbogbo ègún àjẹ́ tí wọ́n gún lòdì sí ayé mi papọ̀, mo sì dá wọn padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán wọn, ní orúkọ Jésù.
3. Ìwọ ẹ̀mí àti ẹ̀mí òkùnkùn tó n ṣàtìlẹyìn fún ohunkóhun tí Ọlọ́run kò gbìn sínú ayé mi, já ìdè rẹ báyìí, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ẹ̀yà àgọ́-ara mi ní ìrírí iná Ẹ̀mí Mímọ́ báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá Olúwa, jẹ́ kí ìpinya wáyé láàrín àgọ́-ara mi àti oúnjẹ búburú tí mo ti jẹ, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá Olúwa, ní orúkọ Jésù, mo pọ gbogbo oúnjẹ búbubú tí mo ti jẹ.
7. Olúwa, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù fọ́ jáde gbogbo májèlé tí wọ́n gbìn sínú ìṣàn ẹ̀jẹ̀ mi látàrí oúnjẹ ibi, ní orúkọ Jésù.
8. Ohun gbogbo tí mo ti sọnù nípa sẹ̀ jíjẹ oúnjẹ ìbọ̀dè, Bàbá Olúwa, jẹ́ kí n gbà wọ́n padà báyìí, ní orúkọ Jésù.
9. Ọlọ́run, ṣe àtúntò ẹ̀yà ayé mi ìyówù tí agbára àìlera ti pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti pọ́n ayànmọ́ mi lójú, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.

11. Mo sọ̀rọ̀ ìparun sí gbòngbò ìrora àti ọ̀ṣì ìyówù tí àwọn agbára àjẹ́ gbìn sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo àìsàn àjogúnbá láti ìran ìdílé mi, gbẹ láti gbòngbò, ní orúkọ Jésù.
13. Ohunkóhun nínú mi, tó n ṣàtìlẹyìn fún ààlè àjẹ́ nípa ìwàláàyè mi, jáde pẹ̀lú gbogbo gbòngbò rẹ, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ẹlẹ́rù ààlè búburú, gbé ẹ̀rù rẹ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
15. Mo fọ́ gbogbo ààlè ìrandíran lórí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
16. Mo gba ètò-ìṣúná mi kúrò lọ́wọ́ ààlè àjẹ́, ní orúkọ Jésù.
17. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo iṣẹ́ àjẹ́ onílara tí wọ́n gbékalẹ̀ lòdì sí ìlọsíwájú mi gba ìparun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
18. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ìránṣẹ́ agbára òkùnkùn láti ibi tí wọ́n ti bí mi , tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
19. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ìránṣẹ́ àwọn agbára òkùnkùn, tó n gbógun lòdì sí ìtẹ̀síwájú lọ sì ibòjì báyìí, ní orúkọ Jésù.
20. Mo fọ́ ojú àwọn ọ̀rẹ́ onílara tó n tọpinpin ayé mi, ní orúkọ Jésù.
21. Ìwọ agbára òkùnkùn ilé bàbá mi, tú ayé mi sílẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.